# Ogota orisi ona ti Ajo Isokan Orile Ede Agbaye fi peregede



Ifilole Ajo Isokan Orile-ede agbaye waye lehin irukerudo ogun lati fi wa ajosepo lagbaye, ki alaafia ati ifokan-bale le fidi mule sinsin.

Ninu ogbun rogbodiyan lilo awon ohun ija oloro fi jagun pelu ifoya rogbodiyan elekun-jekun ni Ajo-Isokan Orile-ede Agbaye fi gbe iko awon olupetu jade lati wa alaafia si rogbodiyan aye.

Bi o tile je wipe ojuse Ajo yi koja pipetu si rogbodiyan ati olulaja, opo igba ni Ajo Isokan-Orile Ede Agbaye ati awon asoju won maa n topinpin awon ohun ti o le mu idagba-soke ba igbesi aye awon eniyan ni kaakiri agbaye.

Eeto idagbasoke ati igbe aye awon ogo weere. Idaabobo ayika wa. Iwadi lori lilo egboogi ati eto ilera. Gbigbogun ti osi ati titalaka lawujo pelu eto idagbasoke iṣẹ oro-aje. Idagbasoke ise ogbin ati ise osin eja. Eeto eko. Ilosiwaju fun awon obinrin. Jamba ojiji ati pipese iranlowo fun awon to ba kan. Irinna oju afefe ati lori omi. Lilo awon ohun oloro lona to bojumu. Ise ati eto awon osise. Gbogbo awon eto yi kọ lonka. Ni soki die lara awon akitiyan ojuse Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye pelu awon asoju won ti won ti se lati igba ti won ti da won sile ninu odun 1945 ni wonyi.

A Translation of "60 ways the United Nations makes a difference" Into Yoruba

# 1 WIWA IDAGBASOKE

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye gbaruku ti tito pinpin igbe aye rere ati imulo ebun ati ilosi omo-eda ni kaakiri agbaye. Eto owona lori ise idagbasoke. Ajo yii lodoodun le ni bilioonu mewa dola yato si ti awon onise okowo. Fun apeere ise idagbasoke Ajo yi wa ni Orile-Ede merin-din-laadosan pelu awon osise won ti won n sise karakara lorii pipana ipo akuse lawujo pelu ifidi mule ijoba rere lawon orile-ede to sese n dide. Igbimo (UNICEF) alabojuto inawo lori eko awon omode wa ni orile-ede meta-din-logojo ti won si n na o le die ni bilioonu kan dola lodun lorii aabo fun awon omode, gbigba abere ajesara, gbigbogun ti arun eedi (HIV/AID) ati eto fun awon omobinrin. Igbimo alabojuto oro-aje UNCTAD tun seran-lowo fun awon orile-ede lori ise okowo. Ni afikun, Banki agbaye pese owoya fun awon orile-ede to sese n dide pelu atilehin to fere to bilioonu meji-din-logun si ogun bilionu dola lodun. Won tun se iranlowo ise idagbasoke egberun mesan le-leedegbeta lati odun 1947. Lakotan gbogbo iranlowo owona yii fun ise idagbasoke je ajoda owo lati odo awon orile-ede kookan.



## 2 IGBELARUGE IJOBA TIWA-N-TIWA

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ti se atilehin fun iduro sinsin ati imu gbooro ijoba tiwa-n-tiwa ni kaakiri agbaye. Ajo yi ti se iranlowo fun awon eniyan lati le dibo pelu irorun ni opolopo orile-ede. Lara won lati ri ile Cambodia, Namibia, El salvador, Eritrea, Mozambique, Nicaragua, South Africa, Kosovo ati East Timor. Won ti pese amoran lori eto idibo ati atilehin pelu tito pinpin esi idibo fun orile-ede to le ni aadorun, paapaa julo lasiko to lewu, ti gbogbo nnkan ruju fun orile-ede kan ninu itan won bii ile Afghanistan, Iraq, ati Burundi.



## 3 IGBELARUGE ETO OMO-EDA

Lati igba ti ipade Gbogbo-gboo ti fowo si ofin Eto Omo Eda Lagbaye ninu Odun 1948 ni Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ti n se atilehin lati gbaruku ti awon ofin to ro mo oro oselu awon ara ilu, oro aje, ohun amuludun ati eto labe asa ibile. Nipa sise iwadi lori awon esun enikookan, igbimo alabojuto eto omo eda fun Ajo yi ti ke tantan fun gbogbo araye lori esun ifiya jeni, ki eniyan di afeeri ati fifi eniyan si atimole lona to lodi sofin. Lori e, won ti ni atilehin awon orile-ede agbaye pe ki won kesi ijoba won lati wa irorun ilana eto omo eda labe ase won.

## 4 IFIDIMULE ETO ALAAFIA ATI AABO

Ogota iko olupetu ija ati awon alamin ni Ajo yi ti ran si awon agbegbe ti ruke-rudo ti be sile ni kaakiri agbaye ninu odun 2005. Nipa igbese yi ni Ajo Orile-Ede Agbaye fi ni anfaani lati le jeki ijoko ipari ija waye. Bi beeko oke aimoye eniyan ni ko ba ti ba ogun lo. Ni lowo-lowo bayi, iko olupetu ija meta-din-logun ni won wa kaakiri agbaye.



## 5 PIPARI IJA

Lati odun 1945, ni Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ti n sakitiyan lorii pipetu si aawo ija to le ni aadosan. Apeere iru won ni pipetu si ogun orile-ede Iran ati Iraq. Fifowo si bi iko omo-ogun Soviet se kuro ni ile Afghanistan ati pipari ogun abele ni ile El Salvador ati Guatemala. Ajo yii, ti lo ogbon ati ona alumo-koroyi yanju oro to le dogun.



# 6 IDAABOBO AYIKA

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye n sa gbogbo agbara lati yanju isoro ayika lagbaye. Gege bi alarina fun agbaye lori ifohun sokan ati pipetu soro lori adehun, Ajo orile-ede Agbaye lo n koju awon isoro kaakiri aye bii aiduro loju kan oju-ojo, ekun ooru to n suyo ni sanmo, awon panti ohun oloro, ikase - nle oko igbo ati awon ohun abemi pelu adalu oorun inu afefe ati omi. Ayafi ti a ba koju awon isoro wonyi, yo nira pupo lati ni aseyori ninu ise kata-kara ati ise oro aje lojo iwaju. Nitori pe ifasehin inu ayika wa ko jeki idagbasoke to wuyi waye ninu ilosi omo-eda.

# 7 DIDENA LILO ERO ALAGBARA INU AFEFE

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye nipase ojuse igbimo alabojuto ilo ero ohun alagbara (IAEA) se akitiyan lati rii daju pe awon orile-ede ti won n lo ero ohun alagbara ko gba ona eburu lati fi maa se awon ohun ija oloro. Ogooro awon ohun eelo ero alagbara yi ni igbimo (IAEA) ti gbese le ni awon orile-ede to le ni aadorin. Ni bayi meta din-loji-le-lugba ilana igbese lori adehun aabo lo n sise lowo ni orile-ede meji-le-laadojo.



## 8 IGBELARUGE IJANGBARA ATI OMINIRA

Nigba ti a da Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye sile ninu odun 1945, oke lona egberun meedogun eniyan bii ida-meta awon eniyan agbaye ni won wa ninu igbekun ijoba afipa je gaba lori eni laisi ominira. Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye lo sakitiyan bi orile-ede to le ni ogorin se di ile olominira.

## 9 IDAJO LORII AWON ARUFIN LASIKO OGUN

Iko igbimo olugbejo labe Ajo Agbaye fun ile Tugoslavia ati Rwanda ti se idajo fun awon arufin ti won ko lasiko ogun si atimole. Won tun gbe akotun ofin jade lori iwa apanirun lasiko ogun ati lori eto eda. Bakanna ni won tun pese ilana eto idajo fun awon toro naa kan lagbagbe yii.

## 10 IFOPIN SI IJOBA ELEYAMEYA NI IHA GUUSU AFIRIKA

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye gbiyanju pupo lorii bi ijoba eleya-meya se kogba wole ni iha Guusu Afirika nipase lilo ofin to de kiko ohun ijagun wolu ati pipana iwa eleya-meya ninu ere idije. Idibo to waye ninu odun 1994, ti o faye gba teru tomo ilee iha Guusu Afirika lo fidi ijoba teni-n-teni lele ni ile naa.



## 11 IFI-KUN AGBARA OFIN AGBAYE

Pelu atilehin Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye, o le ni eedegbeta ajumo fowosi ilana to ro mo eto omo-eda, iwa adigun paniyan, iwa arufin lagbaye, eto ifini wo si ibugbe lehin ogun, ifopin si lilo awon ohun ose ogun jija pelu oro-aje ati awon omi okun lagbaye.

## 12 PIPESE OHUN IRANLOWO FUN AWON TI OGUN KO

O ti le ni egberun oke awon ti ogun le kuro nilu won, tabi awon ti iyan kolu ati awon ti n fimu danrin labe ijoba won ti igbimo alabojuto iru isele wonyi ti pese iranlowo fun labe ase Ajo Isokan Agbaye, lati odun 1951 pelu atilehin awon igbimo miran. Ajo yii n sakitiyan ipada wolu awon to n se atipo bi alaafia ba ti pada wolu won tabi ki won duro si ibiti won ba wa. Koda won tun le lo si orile-ede miran lati lo tedo. O fere to irinwo oke awon to n satipo awon to n fe sa kuro ni ilee won ati awon ti ko lebi mo, ti pupo ninu won je obinrin ati omode ti Ajo Agbaye n pese onje, aaye ibugbe, eto ilera, eto eko, ifini wo pada sipo won fun gege bi iranlowo.



## 13 IYORA NINU APAKU EBI ATI IPO AKUSE NI IGBERIKO AWON ORILE-EDE TO SESE N DIDE

Igbimo eleto inawo lagbaye fun idagbasoke ise ogbin ti a mo si (IFAD) ti se agbekale eto pipese owoya, pooku fun iranlowo awon akuse ni igberiko lati so won di gbajumo. Lati odun 1978, ti eto yi ti bere igbimo IFAD ti na owo to le ni bilionu mejo ataabo dola lori ise egbeta-le-merin-din-logorun pelu awon eeto olokan-o-jokan fun anfaani egberun marun oke eniyan. Gbogbo inawo igbimo, IFAD yii, je atilehin owo atinuda awon orile-ede kaakiri agbaye.

## 14 ATILEHIN FUN AWON PALESITINA TO N SATIPO

Bi gbogbo agbaye se n sakitiyan fun wiwa alaafia laarin ile Israeli ati Palestina bee na ni igbimo eleto abojuto ati ise iranlowo fun awon ti ogun le kuro nilu (UNRWA) labe Ajo Isokan Agbaye n pese eto iderun ati irorun fun awon Palestina to n se atipo. Lara awon ohun irorun ti won n pese lati ri eto eko, ilera, awon ohun afe, inawo fun ise adani, ati iranlowo fun idagiiri. Loni o le ni ogorin oke eniyan to n satipo ni aarin gbugbun ila oorun ti won ni akosile oruko won pelu igbimo (UNRWA) yii.

## 15 DIDOJUKO IDAGBASOKE ILE AFIRIKA

Ile Afirika je aayo fun Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye titi di asiko yii. Ninu Odun 1986, Ajo yi pe akanle-yan ipade kan fun wiwa atilehin agbaye fun irapada ati idagbasoke oro-aje ile Afirika. Ni Odun 2001 awon olori orile-ede ile- Afirika fowo si ilana agbekale ajumose po fun idagbasoke ile Afirika. Ipade gbogbo-gboo Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye fowo si ilana yi ninu odun 2002 gege bi atokun atilehin agbaye fun ile-Afirika. Ida meta-le-logbon ninu ogorun ni iye owona ise idagbasoke ti Ajo Isokan Agbaye na lori ile Afirika, ju gbogbo awon ile miran lo. Bakanna ni awon eka igbimo Ajo yi tun ni orisi-risi eto ise ti won n se fun anfaani ile-Afirika.



## 16 IGBELARUGE IGBE AYE AWON OBINRIN

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ti sakitiyan lati mu ki awon obinrin faga-gbaga pelu awon okunrin lawujo lori eto kanna ati igbe aye rere. Pipese owona fun idagbasoke awon obinrin (UNIFEM) ati ise iwadi pelu eto ekose (INSTRAW) ti buyi kun igbe aye ati eto awon obinrin ni kaakiri awon orile-ede to le ni ogorun. Igbimo eleto iwadi ati ekose (INSTRAW) se ise iwadi ati eto ekose ti igbimo eleto ipese owona (UNIFEM) gbaruku ti akitiyan ifopin si igbogun ti obinrin, pipana itan-kale arun eedi (HIV/AIDS) pelu igbelaruge aabo ise oro-aje won. Fun apeere nipa pipese ise lakotun ati eto won lori oro ile pelu jijogun. Gbogbo awon igbimo Ajo yi gbodo tera mo wiwa irorun fun awon obinrin.

## 17 IGBELARUGE ETO AWON OBINRIN

Lara awon ilana ojuse Ajo Isokan Agbaye ni lati wa igbe aye rere fun awon obinrin pelu fifi won si ipo ti yo se won lanfaani nigbesi aye won. Ajo yi lo pe ipade akoko iru e fun awon obinrin lagbaye ni ilu Mexico ninu odun 1975 pelu awon orisi ipade miran fun ajodun awon obinrin lagbaye lorii wiwa ilosiwaju ninu eto awon obinrin. Ipade Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ninu odun 1979 lorii ilodi si awon ohun to le pegan tabi ya obinrin soto ti ogosan awon orile-ede fowo si lo jeki eto awon obinrin ni kaakiri agbaye fese rinle sinsin.

## 18 PIPESE OMI MIMU

Laarin asiko odun ti Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye ya soto fun ipese omi-ero (1981 - 1990) o le ni bilionu awon eniyan ti won ni anfaani omi ero fun mimu lakoko nigbesi aye won. Afikun tun waye laarin odun 1990 ati 2002 nigba ti awon eniyan ti won ni anfaani omi mimu tun le ni bilionu kan. Ninu odun 2003, taa ya soto fun ipese omi mimu lakotun, opolopo eniyan lo tun mo pataki aabo omi -mimu. Igbese keji ipolongo pipese omi lagbaye laarin odun (2005 si 2015) je one lati din iye awon ti ko ni anfaani omi lilo ku si idaji.



## 19 IGBOGUN TI ARUN ROPA-ROSE

Arun yii ti kase n le ayafi ni awon orile-ede mefa kan Afghanistan, Egypt, India, Niger, Nigeria ati ni Pakistan lori igbese ipolongo pipana arun yii lagbaye. Ope ni fun awon Igbimo Ajo Isokan Agbaye, bii igbimo eleto ilera agbaye, UNICEF, egbe Rotary ati ogba orile-ede US to n bojuto idena itan-kale arun ati pipana won. O fere to bilionu marun awon omode ti won n rin fanda bayi, ti arun ropa-rose ko ba ti da won gunle. Arun yii ti kolu awon omode ni kaakiri orile-ede bii marun-din-laadoje lagbaye.

## 20 IDOJUKO ARUN EEDI HIV/AIDS

Akanse eto igbogun ti arun eedi HIV/AIDS (UNAIDS) ni kaakiri agbaye eyi ti o kolu egberun oke eniyan. O le ni aadoje oke orile-ede ti won n je anfaani igbogun ti arun eedi ati iwosan re, pelu bi arun naa ko se ni tan kale. Igbimo UNAIDS se akojopo iko awon ojogbon mewa ti won je asoju fun Ajo Isokan Agbaye lati pana arun yii.

## 21 PIPANA ARUN ILE-GBONA

Iyanju igbimo eleto ilera agbaye laarin odun metala lo pana arun ile-gbona lorile-ede agbaye ninu odun 1980. Pipana arun yii lo din inawo bii bilionu kan dola ku lorii eto gbigba abere ajesara lati dena arun naa lodoodun.

## 22 GBIGBOGUN TI AWON ARUN ARA

Akanse eto igbimo eleto ilera agbaye ni kaakiri orile-ede mokanla ni ila - oorun ile Afirika lo pana itankale arun to n foni loju ti o si daabo-bo oji-le-lugba awon omo-weere. Bakanna ni won tun pese eedegbeta oke sare ile fun ise ogbini. Iko igbimo asoju fun Ajo Agbaye lo tun sakitiyan igbogun ti awon arun aran muje-muje ninu odun 1991 ti awon arun naa fi kogba wole. Lara awon arun ti won tun gbogun ti lati gba emi awon eniyan la ni arun sobiya ati awon ajakale arun miran.

## 23 DIDENA AJAKALE ARUN

Igbimo eleto ilera fun agbaye se gudu-gudu meje yaaya mefa lati dena itan-kale awon arun gbofun-gbofun to le pa ogooro eniyan. Itaniji ati ipolongo nipa atan kale arun yi ninu osu keta odun 2003 lo jeki awon orile ede toro naa kan yara tete doju ko ipana itan kale arun yii pelu eto itoju arun yii lakotun. Igbimo eleto ilera agbaye se iwadu arun naa larin igba si aadota-le-lugba eniyan to ni arun yii ni odun kookan. Lori iwadi yi marun ninu meedogun laarin odun kookan ajakale arun yi ni iko agbaye n bojuto.

## 24 IGBIYANJU LORII GBIGBA ABERE AJESARA

Laarin ogun odun sehin gbigba abere ajesara ti gba emi awon eniyan to le ni irinwo oke la. Pelu iranlowo ati akitiyan igbimo eleto inawo ati igbimo eleto ilera agbaye ni imugbooro abere ajesara lati dena arun ropa-rose, arun ipa, arun eyi, iko gbofun-gbofun, igbe-orin ati iko egbe fi tubo gbooro sii, lati odun 1970 ti di oni. Lati odun 1999 si odun 2005 awon eniyan to ku nipase arun eyi ti dinku gidi si ilaji. Gbigba abere ajesara lati dena arun eyi ti gba emi opolopo eniyan la, paapaa awon abiyamo ati awon omo tuntun jojolo. Awon orile ede to sese n dide merin-le-logorun ni won ti pana itankale arun yi lagbegbe won.

## 25 ADINKU ABIKU OMO

Lati ibere odun 1960, o fere je wipe omo kan ninu marun lo n ku ki won to di omo odun marun. Lori ilana eto itoju ilera ti iko awon igbimo asoju fun Ajo agbaye gbe jade pelu eto imototo lo jeki iye awon omo abiku dinku si eyokan ninu mejila ni kaakiri awon orile-ede to sese n dide ninu odun 2003. Ireti wa ni lati wa adinku ninu awon omo abiku to ti n waye laarin odun 1990 si ida meji ninu meta ki o to di odun 2015.

## 26 GBIGBARUKU TI ISE OKOWO

Ajo Isokan Orile-ede agbaye peregede ninu ise okowo. Won ti pese ilana wiwa irorun fun ise oro aje agbaye nipa iduna-dura awon ona alumo-koroyi ti agbaye faramo ninu agbekale isiro onka, ofin ise oja tita, eto ise ibode, awon ohun ini to niye lori, ise oko ofurufu, oko oju-omi ati ilana eto ifoun-ranse pelu irorun ninu ajumose po ise oro-aje ati adinku inawo lori awon ona wonyi. Ajo yi ti bojuto ifilele ise idalokowo laarin awon orile-ede to sese n dide nipa atilehin fun eto iselu ti yo fese rinle sinsin ati ijoba rere. Gbigbogun ti iwa-ibaje lawujo pelu wiwa ilana oro aje to buyaari ati ofin ti yo gbe ajosepo ise okowo olore-sore dide.

## 27 ATILEHIN FUN IBI-ISE OKOWO NI AWON ORILE-EDE TO SESE N DIDE

Pelu atilehin igbimo eleto idagbasoke ise okowo (UNIDO) labe Ajo Agbaye, won je alarina laarin iha Ariwa ati guusu ati guusu-si guusu lori ajosepo ise okowo, idasile ise okowo, iranlowo lori ise imo ero tode oni pelu owo pooku fun idagbasoke ise okowo ti yo gberu. Won ti se iranlowo fun awon orile-ede lati se aseyori ninu eto ise aye-lu-jara won ati adinku awon akuse lawujo ni die-die.

## 28 IRANLOWO FUN AWON TI JAMBA KAN

Bi jamba ojiji tabi ewu airotele ba sele, Ajo Isokan Agbaye lo n se agbateru iranlowo ati kokaari iyora ninu ewu fun awon toro naa ba kan. Won maa n sise pelu awon alagbelebu pupa awon alami osupa pupa pelu pipese awon ohun iranlowo lati owo awon alaanu fun awon to wa ninu ewu. Ajo yi n ri owo to le ni bilionu meji dola lodun kan ti won ba ke gbajare fun iralowo ewu ojiji.

## 29 ADINKU AWON EWU OJIJI

Iko ajo eleto oju-ojo (WMO) ti se iranlowo lati gba emi oke aimoye eniyan la ninu ewu ojiji to je amuwa Olorun ati afowo-fa ti omo eniyan. Ikilo ti won n gbe jade loore-koore nipa ewu to le suyo loju ojo jeki jamba awolu awon ohun isura ati ewu iwa kusa jeki awon eniyan dena iru ewu wonyi. Se agbo-tele kii se iku paro. Awon ni o n je ki iranlowo onje tete de agbegbe awon ti iyan ba n ba ja.

## 30 IPESE IRANLOWO FUN AWON ARA SUNAMI (TSUNAMI)

Ni aarin wakati merin-le-logun iyen ojo kan ti isele omi okun India ya wolu ni ojo kerin-din-logbon osu kejila odun 2004, ni iko alabojuto isele jamba ojiji fun Ajo Agbaye ti de agbegbe naa fun ofin toto pelu awon osise won, lati wo awon ibiti isele naa baje gan-an. Ni kia ni Ajo Isokan Agbaye ti bere abojuto fun awon ti o la ewu yii, ti won si n pin onje fun awon eniyan to fere to ogoji oke. Bakanna ni won pese aaye ibugbe fun ogun oke eniyan ti won ko ni aaye ibugbe mo. Won tun pese omi mimu pelu fifun awom omode ni abere ajesara lati dena arun eyi. Awon ti won je anfaani yi le ni ogoji oke eniyan, laarin osu mefa ti isele yi waye. Yiyara pese iranlowo yii ko jeki emi sofo ju awon ti jamba na koko kolu, lasiko ewu nla yi koda ko jeki ajakale arun tan kale rara.

## 31 IDAABOBO IMISI AFEFE

Igbimo eleto aabo ayika fun Ajo Agbaye (UNEP) ati ajo eleto imo nipa oju-ojo (WMO) n sakitiyan pupo lorii ewu to wa ninu adalu-dapo imi afefe. Lori adehun to waye ni ilu Montreal gbogbo ijoba agbaye ti fopin si lilo awon kemika to lewu fun imisi afefe ati pipaaro won pelu awon ohun to le se afefe lanfaani. Iyanju yi a je aabo emi ati ara ninu awon arun bii kansa to n wora lati inu imisi adalu-dapo afefe.

## 32 IDOJU-KO AIDURO DEDE OJU-OJO

Eto inawo lori awon ohun eelo ayika lagbaye (GEF) wa lati fi se iranlowo fun idagbasoke awon orile-ede to sese n dide ki won fi bo lowo ewu aiduro loju kan oju-ojo. Ninu odun 1991 ni won da igbimo (GEF) sile fun idojuko eto ayika lagbaye. O tun wa fun atilehin idaabobo adalu-dapo imisi afefe, aabo omi lagbaye, idojuko ile ki o mo di asale ati pipana awon ohun to le da idoti sile ninu afefe. Lati inu odun 1991 ni GEF ti pese owo iranlowo to fere to bilionu mefa owo dola fun awon ise keke-ke to le ni egberun mefa ti awon egbe adimula ilu ati awon egbe ti ko fara ti ijoba dawo-le. O fere to bilionu mokan-din-logun owo dola ti awon agbateru eto inawo yii gba wole. Awon eleto ikowojo fun inawo ayika agbaye (GEF) ni igbimo eleto inawo ise idagbasoke fun Ajo Agbaye, eleto inawo fun ayika agbaye ati ile-ifowo-pamo-Banki agbaye.



## 33 PIPANA OGUN ATI OTE

Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye lo n dari igbiyanju lorii pipana ogun ati ote ni awon orile-ede bii ogbon. Lara won ni, ile Afghanistan, Angola, Bosnia ati Herze-govina. Iraq, Mozambique ati orile-ede Sudan nibi ti won ti n pa eniyan bi eni peran lodoodun. Ajo yii kanna tun sise kara-kara fun aabo emi awon eniyan lowo ewu ati lati le da duro sise ara won.

## 34 PIPESE ONJE FUN AWON TI EBI N PA

Ilana eto pipese onje lagbaye je iko kan to tobi ju lorile aye ti o si n pese onje fun bii ogosan oke eniyan ni ogorin orile-ede lodoodun. Lara awon iru eniyan bee lati ri awon ti ogun le kuro nilu won ati awon to n se atipo lehin odi. Iko igbimo yi n pese awon onje amara lokun bii jeero, ewa, iresi, epo, iyo ati awon onje miran to kun fun eroja amara lokun. Igbimo eleto onje yii (WFP) je ilana eto kan lati pese itelorun fun awon obinrin ati awon omode ti won n koju ebi. Eto ipese onje fun awon omo ile-eko lofe tabi onje amu-rele tun wa fun bii oji-le-loodun oke awon omo ile-iwe. Onje kookan to senti mokan-din-logun owo dola. Bi won se n lo oko ofurufu lati fi ko awon onje wonyi, bee ni won n lo kete-kete pelu ilo ero igbalode lati fi mo abajade ipese awon onje wonyi kaakiri agbaye. Laarin ogoji odun sehin iko igbimo yii (WFP) ti pese iwon onje to fere to ogojo oke toonu fun iranlowo awon eniyan to le ni bilionu kan ni opo awon orile-ede to kuse. Apapo owona lori eto yii le ni bilionu meta-le-logbon owo dola.

# 35 IGBOGUN TI EBI

Ajo eleto onje ati ise ogbin fun Ajo Agbaye (FAO) se agbekale ilana eto fun ojo iwaju lori iyanju lati pana ebi lawujo. Ajo yi (FAO) duro bii alarina laarin awon orile-ede to ti dide ati awon eyi ti o sese n dide nibi ti gbogbo awon orile-ede ti n pade gebe bi ori kojori lati jumo se adehun ati agbekale ilana to muna doko. Ajo FAO n se iranlowo fun awon orile-ede to sese n dide lati so ise agbe won dotun pelu awon ohun elo imo ero, ise awogbo ati eja pipa lona tode oni fun ipese onje lakotun.



# 36 DIDENA DIDE ODO GBE

Ida merin-din-logun ninu awon odo eja lagbaye ni won ti fun won gbe, ti ida mejo ninu ogorun ko ti le se dedo mo. Igbimo eleto ogbin ati onje (FAO) lo n se akitiyan tito pinpin odo eja lagbaye pelu gbigbe ikilo jade lori ewu ti o wa ninu dide odo gbe fun eja pipa. Lati le kapa isoro yii, igbimo (FAO) ati iko awon omo egbe won lorile ede kookan ti pamopo gbe ilana ofin jade lori pipa eja eyi ti won fowo si ninu odun 1995.

## 37 FIFI OFIN DE PANTI AWON OHUN ILO ERO

Ipade ti o waye ni ilu stockholm lorii adapo oorun inu afefe fenu ko lati fopin si ilosi awon ohun egbin oloorun to lewu si igbe aye. Won fowo si ipinnu yi ninu odun 2000. Bakanna ni ipade yi foju da awon ohun oloro mejila kan to le seku pa eniyan, se akoba fun isan ara pelu awon ohun imara lokun. O le fa arun kokoro jejere, idiwo fun omo bibi ati idena fun idagba-soke awon omode. Ipade Ajo Agbaye tun se akitiyan lori idabobo awon orisi arun wonyi pelu idojuko aiduro deede oju-ojo, aabo fun awon eranko, idojuko itankale ile asale, amojuto etikun ni ekun kookan pelu ifopin si dida awon ohun idoti elegbin si aala ile orile-ede miiran.

## 38 IDAABOBO FUN ETO ILERA

Lati ri aridaju aabo lori awon onje ti won n ta loja, igbimo eleto onje ati ise ogbin pelu eleto ilera agbaye n sise pelu awon orile-ede kookan. Lori akitiyan won, o le ni orisi-risi onje bii igba ti won ti fi onte te, egberun meta agbaa onje ni won ti fonte le lori nipa aabo wonyi. Bakanna ni won gbe ilana awon aabo jade lorii ipese onje to dara, kiko onje wolu ati ipese onje pamo. Fifi onte ilewo si ara awon onje ti a n ra nipa alaye lori won je iranlowo lati daabo-bo awon onraja.

## 39 IGBOGUN TI AWON AMOOKUN JAGUN

Ajo Isokan Orile-ede agbaye ti gbe ilana ofin kale lati fi gbogun ti awon amookun jagun lagbaye. Igbese metala lori agbekale ofin lagbaye ni Ajo Isokan Agbaye ti fi lele. Lara won ni ifowo-sowopo lati lodi si imuni leru, ifipa gba baalu oko ofurufu, awon alajangbila to n lo ohun ose bombu, atilehin owona fun awon amokun jagun ati lilo awon ohun ija oloro lowo awon amookun jagun. Awon orile-ede meta-le-logota ni won ti jumo fowo si ofin yi lati inu osu kefa odun 2005. Awon ilana titun miiran labe ofin to de amookun jagun ti n lo lowo bayi. Igbimo alatako iwa amookun jagun labe Ajo Isokan Agbaye lo n to pinpin lorii bi awon orile-ede to fara-mo ilana ofin yii lehin isele ti awon amookun jagun fi kolu ile Amerika ti won si nsowopo lati pana iwa awon arufin wonyi. Ofiisi eleto egboogi ati amojuto iwa odaran pelu awon eka Ajo agbaye ti se atilehin fun ogorun orile-ede lati fi pana iwa amookun jagun.

## 40 IGBELARUGE IMUGBOORO EBI ATI ILERA TO PEYE

Eto inawo lori isiro iye eniyan lawujo, inawo lori isiro iye eniyan lawujo (UNFPA) je igbelaruge eto enikookan lati pinnu lori iye omo ti won ba fe bi ati igba to wu won lati bimo labe ilana fifi eto somo bibi lowo ara won. Igbese yii je iranlowo fun awon eniyan lati fowo ara won yan ohun ti won n fe lokan won. Eyi fun awon ebi, paapaa julo awon abiyamo ni eto atokan wa lori iru igbesi aye ti won n fe. Nipase bayi awon abiyamo ni awon orile-ede to sese n dide ni anfaani lati bi omo die bii mefa lati nnkan bi odun 1960 si omo meta lode oni. Eyi n din iye eniyan lawujo agbaye ku. Nigba ti igbimo UNPFA bere ise lori ilana eto yii ninu odun 1969, nnkan bii ida kan ninu marun ǹi awon toko-taya ti won n feto somo bibi. Ni bayi iko mokan-le-logota ninu ogorun ni awon to n kopa. Igbimo UNPFA pelu opo awon alatilehin tun n se iranlowo lati pese awon akose-mose osise olugbebi, pipese awon ohun itoju fun ewu riro-bi ati imu-gbooro ifeto somo bibi lati din iku awon abiyamo to nrobi ku.

# 41 AGBEJADE ETO IDAJO FUN IPETU SI EDE-AIYEDE LAGBAYE

Nipa sise eto idajo to peye pelu agbekale amoran labe ofin, ile ejo eto idajo lagbaye ti se atilehin lati pana aawo to waye lori oro aala ile, ifipa ba obinrin sasepo, eto lati sawo orile-ede kan fun asala emi ati eto lori ise oro-aje.

# 42 IGBELARUGE AJUMOSE PO ISE OKOWO LAGBAYE

Igbimo alamojuto ise okowo ati idagbasoke (UNCTAD) fun Ajo Agbaye ti se atilehin fun awon orile-ede to sese n dide lori iduna-dura ninu ise okowo ati anfaani igbelaruge ise yii fun kiko oja jade si ile okeere. Bakanna ni won ti se iranlowo lori awon oja kan ti won fi le gbowo lori fun tita loja agbaye. Won tun se iranlowo lorii bi awon oja naa se maa kuwon pelu agbejade awon oja yii lakotun ti yo fi le see ta lawujo oro-aje agbaye.



## 43 ITESIWAJU NINU ATUNGBEYEWO ETO ISE ORO AJE

Ile-ifowopamo (Banki) agbaye ti se opolopo iranlowo fun aimoye orile-ede lati gbe akoso oro-aje won laruge, pelu ipese owona fun won lati fi kapa isoro aito owo ati pipese eeto ekose fun awon osise ijoba onisiro owo.

## 44 WIWA IFOKAN-BALE LORI OKUN AGBAYE

Nibi ijoko ipade kan ni Ajo Isokan Orile-ede agbaye ti sakitiyan agbekale ilana lilo agbami okun. Ipade Ajo Agbaye ninu odun 1982 lori ofin to ro mo lilo agbami okun jeki gbogbo agbaye tele ilana ofin yi lorii irinna lori okun ati wiwonu okun. Ofin yi da lorii agbegbe ti awon oko oju-omi gbodo maa rin, irin ajo loju agbami okun, eto ti oro mo ilosi eti bebe okun ni awon orile-ede kookan, idaabo-bo awon ohun emi ati ayika agbami okun, ifowo-sowopo ninu akitiyan iwadi ijinle ati idaabobo awon ohun alumoni inu agbami okun.

## 45 IGBELARUGE IRINAJO AFEFE ATI OKUN

Awon asoju Ajo Isokan Orile-ede agbaye ni won n sakitiyan agbekale aabo to peye fun irinna oju afefe ati lori omi okun. Ajo eleto irinna oju afefe lagbaye (ICAO) ti gbiyanju gidi lati rii daju pe aabo to peye wa lorii irinna oju afefe. Ninu odun 1947 ti ogosan oke eniyan woko baalu sugbon mewa din-leedegbeta ni awon eniyan to ku ninu isele jamba oko ofurufu. Ninu odun 2004 oji-le-nirinwo eniyan lo ku lara awon ero to le ni bilionu meta. Bakanna ni igbimo eleto abojuto irinna oju omi lagbaye (IMO) ti jeki aabo to peye wa ninu irinna oju-omi. Akosile eri fi ye ni pe irinna oju-omi ni aabo to daju gidi bayi pelu itesiwaju lori itoju agbegbe omi. Oro pe oko oju omi sonu ti n dinku, oko riri ti n dinku, adalu dapo panti ati oorun loju omi ti n pare, isan epo robi loju omi ti n dinku. Beeni iye oko oju-omi to n keru tubo n po sii. Nipa ipese ona to gbanuse fun kata-kara awon ise ona wonyi lati buyi kun ise okowo lagbaye.

## 46 KIKOJU IWA LILO EGBOOGI OLORO

Ofiisi Ajo Isokan agbaye to n bojuto ilo egboogi ati iwa odaran lawujo ti gbiyanju lati din tita ati rira awon egboogi yi ku nipa tito pinpin ilana ofin to de lilo egboogi oloro pelu ipolongo awon alebu ti o wa ninu iwa odaran yii, ati kiko arun eedi (HIV/AIDS) nipase ilokulo naa. Iyanju yi suyo nipa atilehim fun awon eleto aabo ilu ati ifowo-sowopo pelu egbe awon to n tako lilo egboogi oloro lawujo.



## 47 GBIGBOGUN TI IWA ODARAN LAGBAYE

O fiisi alabojuto ilo egboogi ati iwa odaran labe Ajo Agbaye n sakitiyan pelu awon orile-ede ati awon egbe amuludun lati gbogun ti iwa odaran nipa amulo ilana ofin ati awon ohun eelo tito pinpin iwa ibaje, gbigbeowo salo sile okeere, isowo oja ati kiko eniyan wolu lona eburu pelu afikun agbara eto idajo iwa arufin. Ofiisi yii ti ko ipa pataki lati se iranlowo fun idagbasoke ati ifese rinle ipinnu awon orile-ede agbaye.



## 48 AGBEKALE ISE SISE LAKOTUN

Ajo egbe osise lagbaye (ILO) ti gbe ipo ise laruge lori sise ise lori eto ati ominira awon egbe osise lati ja fun eto awon omo egbe, fifi opin si lilo osise bii eru, ilodi si lilo awon omode lenu ise ati ayokuro iwa eleya-meya lenu ise. Ajo (ILO) egbe awon osise lagbaye ti ja takun-takun lori ilana eto igbani sise, aabo to nipon lenu ise, ifikun-lukun laarin ajumo-sepo laarin egbe osise ati awon ijoba.



# 49 IGBELARUGE EETO EKO NI AWON ORILE-EDE TO SESE N DIDE

Lori akitiyan awon igbimo to soju fun Ajo Agbaye, o ti le ni aadorin ninu ogorun awon agbalagba ti won ti mooko-mooka bayi, ti iko meji-din-logorun ninu ogorun awon omode to n lo si ile-iwe alakobere ni awon orile-ede to sese n dide. Ohun ti a n lepa bayi ni lati rii daju pe gbogbo awon omode lo jade ile-iwe alakobere ninu odun 2015.



# 50 LILEPA ATILEHIN AGBAYE FUN AWON OGO-WEERE

Ajo eleto inawo fun awon ogo-weere lagbaye UNICEF ti sise kara-kara lati ile El-salvador si ile Lebanon ati lati ile Sudan titi de orile-ede Yugoslavia (teleri) fun itankale wiwa alaafia ati ifokan bale lati le pese abere ajesara ati awon ohun miiran fun iranlowo awon omode ni awon agbegbe ti ogun wa. Ifohun sokan lori eto awon omode ti di ofin ni awon orile-ede meji-le-laadowa. Lehin ijoko Ajo agbaye ninu aadowa awon ijoba ni won ti pinu latisise kara-kara laarin asiko ti won da funra won fun lilepa eto ilera, eto eko, aabo lori itapa si eto, ifiyajeni lona aito ati pipana arun eedi - HIV/AIDS.






## 51 IDAABO-BO AWON AAYE ATIJO TONITAN, AWON OHUN IBILE ATI AWON ISE ONA ATIJO

Ajo UNESCO ti se iranlowo fun orile-ede mokan-le-logorin lati daabo-bo awon ohun ajogun-ba won. Beesi ni ipade Agbaye ti fenuko lati daabo-bo awon ohun ibile ta daye ba.

## 52 FIFI AAYE GBA IMO EKO ATI ABASEPO ERE IBILE

Ajo Isokan Orile-ede Agbaye n lo asoju won UNESCO ati ile eko nlaa. Ajo Agbaye fun ifowo-sowopo ninu wiwa imo eko sayensi laarin awon ile-eko gbogbo-gboo ati ilosiwaju ninu ere ibile ati awon ohun ajogunba.






## 53 AABO FUN ISE AWON ONIMO

Igbimo fun aabo ise awon onimo ise lagbaye (WIPO) n se idaabo-bo fun ise awon onimo ojogbon lori eto won kaakiri agbaye pelu aridaju pe awon onimo ise wonyi ati awon olootu iwe imo ijinle gbayi lawujo pelu mimo riri ise won. Idasile ofin fun idaabobo eto awon ojogbon onimo ijinle je ona kan lati gbe ise ona eda laruge pelu itesiwaju ninu imo sayensi ati ilo ero fun anfaani imo iwe agbeleko, ati ise ona lagbaye.

## 54 IGBELARUGE OMINIRA AWON ONIROYIN ATI ISORO FALALA ENIKOOKAN LAWUJO

Igbimo eleto imo eko fun Ajo Agbaye (UNESCO) ti se iranlowo to buyaari lati rii daju pe enikookan lawujo ni eto si iroyin laisi ayokuro tabi adinku nipa afikun agbara awon oniroyin ati idagbasoke won fun idasile iwe iroyin aladani. Igbimo UNESCO yii tun n sode fun ominira awon oniroyin, pelu idojuko ohun abuku yowu to le waye nidi iroyin nipa pipa oniroyin ati atimole won.

## 55 IGBELARUGE IMO EKO FUN AWON ABILEKO

Awon eto ti a da sile lati fi wa imo eko ati ilosiwaju fun awon abileko ti jeki awon to mowe ninu won gbera lati ida merin-din-logoji ninu ogorun ninu odun 1970 si ida aadorin ninu ogorun ninu odun 2000 ni kaakiri awon orile-ede to sese n dide. Ohun ti a n lepa bayi ni lati rii daju pe gbogbo awon omobinrin jade ile-iwe alakobere ati ile-eko giga ninu odun 2015.

## 56 IGBELARUGE ETO IFIWE RANSE

Egbe ajumosepo eto ifiwe ranse lagbaye (UPU) je gbongbo kan fun ifowo-sowopo ise eto ifiwe ranse. O je iranlowo kan lati rii daju pe itankale oja atowo-dowo ko duro loju kan. Igbimo yi lo gbe ofin pasi-paaro ifiwe ranse kale lagbaye pelu agbejade imoran fun itesiwaju lori bi ifiwe-ranse se npo sii ati wiwa irorun fun awon onibaara won. Aadowa ni awon orile-ede ti won je omo-egbe UPU ninu ise eto ifiweranse ni kaakiri agbaye. O fere to iwe ifiranse bii ogbon-le-nirinwo bilionu ti won n sabojuto lodun kan.

## 57 IFILELE ISE OGBIN LONA ARA PELU EDINWO

Lori iranlowo igbimo eleto onje ati ise ogbin, awon ohun ogbin tun gbeeru sii, pelu ilana to jeki awon ara ilu le kopa ninu ise ogbin. Koda awon agbe oniresi ni ile Asia n ri owo to le ni ogorun oke Dola pa wole laarin odun kan lorii inawo oogun apa kokoro jeko-jeko ti ijoba won si ri owo to le ni oodunrun oke dola lodun lori edinwo oogun apa-kokoro yii. Anfaani to suyo nipa ilana yi ni ayika ati eto ilera le ni igba oke owo Dola laarin odun kan.

## 58 IGBELARUGE ETO AWON ABIRUN LAWUJO

Ajo Isokan Orile-ede Agbaye ni agbateru jija fun wiwa eto kanna fun awon abirun lasiko akojopo lawujo ere, ise oro-aje ati eto oselu. Ajo Agbaye ti fi han pe awon abirun je ohun oro lawujo ati pe won n gbaradi fun apejo pataki kan lati gbe eto won laruge ni kaakiri agbaye.



# 59 IGBELARUGE ETO IFOHUN RANSE

Egbe eleto ifohun-ranse lagbaye (ITU) lo so awon ijoba ati awon ibise okowo papo lati wa idagbasoke ati sise kokaari ise ifohun-ranse lawujo agbaye. Awon ni won sise ajumo-sepo igbohun safefe lori Redio, ajosepo pinpin ate ero imohun-maworan ranse pelu wiwa ilana ilosiwaju ninu ise yii lawujo agbaye. Won sise kara-kara lori ifohun ranse oko ofurufu, ti oju-omi ero amohun-maworan, fifi waya ranse, ati ero foonu ti aye fi lu jara won titi di iran to nbo. Egbe ITU yi gbegba oroke ninu eto ifohun ranse beeni ise won yii ti jeki eto igboke-gbodo igbohun safefe-ranse gbooro kari aye ninu ise okowo olowo goboyi lagbaye.



# 60 ABOJUTO IPO AWON OMO-ONILE LAWUJO

Ajo Isokan agbaye ti ke tantan iya ti won fi n je awon omo onibi-niran bii egberun mejo oke eniyan ni kaakiri orile-ede bii aadorin lagbaye, ati pe iko eniyan wonyi ni won ko ri anfaani eto won gba lawujo agbaye. Iko awon asoju merin-din-logun lori oro yi ti won da sile ninu odun 2000 ti n sise fun ayi pada.





          

**For more information on the**
**Millennium Development Goals:**
www.un.org/millenniumgoals
www.millenniumcampaign.org
millenniumindicators.un.org
**For more information on**
**how the UN works for all:**
www.un.org/works

Produced by the United Nations Information Centre, Lagos, Nigeria
Tel: 01 - 2694886

Printed by donald rowlands LTD. 08023007520.